

# Lẹ́yìn Ìṣẹ́jú Kan

Gbogbo ẹ̀dá ló ń fẹ́ ẹ̀mí gígùn àti ìgbésí aiyé aláyọ̀; ṣùgbọ́n ó jẹ́ òtítọ́ tí kò ní àríyànjiyàn pé ikú lè ṣe àbẹ̀wò sí ọ̀dọ́, àgbàlagbà, ọlọ́rọ̀, tálákà, ènìyàn mímọ́, àti ẹlẹ́ṣẹ̀ nígbàkugbà, àti níbikíbi. *Ikú ti Ara* jẹ́ ègún tí kò ṣẹ lórí i Ádámù àti Éfà nìkan, ṣùgbọ́n lórí i gbogbo ẹ̀dá (Romu 5:12).

Lẹ́yìn ikú, ìdájọ́ lókàn (Heberu 9:27). Nígbàtí ènìyàn bá kú, àwọn àyànfẹ̀ rẹ yóò bẹ̀rẹ̀ síí ṣe ètò ìsìnkú rẹ̀. Wọ́n yóò ṣe àwọn ètò yìí, wọ́n yóò sì múra láti ka ìwé ìpín-ogún tí ó fi sílẹ̀. Bí wọ́n ṣe ń ṣọ̀fọ̀ lọ́wọ́, ọkàn ẹni tí o kú yìí ti wà ní ìkan nínú àwọn ibi méjì wọ̀nyí: Párádísè (ibi ìsinmi fún àwọn olódodo, ṣáájú àjíǹde sí ìyè àinípẹ̀kún) - *wo*

*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

## Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



Lẹ́yìn Ìṣẹ́jú Kan

Gbogbo ẹ̀dá ló ń fẹ́ ẹ̀mí gígùn àti ìgbésí aiyé aláyọ̀; ṣùgbọ́n ó jẹ́ òtítọ́ tí kò ní àríyànjiyàn pé ikú lè ṣe àbẹ̀wò sí ọ̀dọ́, àgbàlagbà, ọlọ́rọ̀, tálákà, ènìyàn mímọ́, àti ẹlẹ́ṣẹ̀ nígbàkugbà, àti níbikíbi. *Ikú ti Ara* jẹ́ ègún tí kò ṣẹ lórí i Ádámù àti Éfà nìkan, ṣùgbọ́n lórí i gbogbo ẹ̀dá (Romu 5:12).

Lẹ́yìn ikú, ìdájọ́ lókàn (Heberu 9:27). Nígbàtí ènìyàn bá kú, àwọn àyànfẹ̀ rẹ yóò bẹ̀rẹ̀ síí ṣe ètò ìsìnkú rẹ̀. Wọ́n yóò ṣe àwọn ètò yìí, wọ́n yóò sì múra láti ka ìwé ìpín-ogún tí ó fi sílẹ̀. Bí wọ́n ṣe ń ṣọ̀fọ̀ lọ́wọ́, ọkàn ẹni tí o kú yìí ti wà ní ìkan nínú àwọn ibi méjì wọ̀nyí: Párádísè (ibi ìsinmi fún àwọn olódodo, ṣáájú àjíǹde sí ìyè àinípẹ̀kún) - *wo*

*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL
~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé

www.divineliterature.org
www.doveletters.org

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

*Lúùkù 23:42-43*, tàbí Hédíìsì (ibi ìdálóró, níbi tí àwọn ẹlẹ́ṣẹ̀ ń gbé láti jìyà títí di Ọjọ́ Ìdájọ́, nígbà tí Ọlọ́run yóò sọ wọ́n sínú adágún iná) - *wo Lúùkù 16:23-28*.

Òkú tí ó wà ní Hédíìsì ti ń jẹ oró bayìí. Ó ṣeé ṣe kí ó máa bínú, bí ó ṣe ń rántí àwọn tí wọ́n mọ ohun tí òun ìbá ti ṣe láti má nírìírí oró tí ó pọ̀ tó yìí, ṣùgbọ́n tí wọ́n kùnà láti sọ fún un. Ó sì lè máa kábàámọ̀, bí ó bá jẹ́ pé wọ́n sapá láti kìlọ̀ fún un lọ́pọ̀ ìgbà, ṣùgbọ́n ó yàn láti kọ etí sí ẹ̀bẹ̀ wọn pé kí ó ronúpìwàdà àwọn ẹ̀ṣẹ rẹ̀, kí ó sì jọ̀wọ́ aiyé rẹ̀ fún Krístì. Ó ṣeni láàánú pé kò sí ẹ̀bẹ̀ àti àyè mọ́ láti wá bá Krístì lẹ́yìn tí ènìyàn bá ti kú. Ní ìdàkejì, òkú tí ó wà ní Párádísè ń sinmi ní ibi ìdùnnú ńláǹlà; ibi tí ìtẹ́lọ́rùn wà, tí kò sí ìrora tàbí ìbànújẹ́. Pẹ̀lú ayọ̀ ni ó ń retí èrè tí kò ṣeé díye lé, ní ọjọ́ ìdájọ́.

Ìwọ ńkán? Ṣé o ní ìgbàlà? Ṣé o mọ ohun tí ó ń dúró dè ọ́ nígbà tí o bá kú? Ǹjẹ́ àwọn tí ò ń bá rìn ń bá ọ sọ̀rọ̀ nípa bí ìgbàlà ti ṣe pàtàkì tó? Ǹjẹ́ wọ́n ti sọ fún ọ pé kò sí òtítọ́ nínú ẹ̀kọ́ *'Àtúnwáiyé bíi ẹlòmíràn lẹ́yìn iku'*? Ǹjẹ́ wọ́n ti jẹ́ kí o mọ̀ pé kò sí ẹnìkan tí ó lè ní ìgbàlà nípasẹ̀ iṣẹ́ rere rẹ̀, bíkòṣe Ẹ̀jẹ̀ Jésù Krístì? Krístì ni Ọ̀na kan ṣoṣo sí Ọ̀run. Ó sọ wípé: *"Èmi ni Ọ̀nà, Òtítọ́, àti Ìyè. Kò sí ẹnikẹ́ni tí ó lè wá sọ́dọ̀ Bàbá, bí kò ṣe nípasẹ̀ Mi"* (Jòhánù 14:6). Èyí tó túmọ̀ sí pé, a kò lè rí ìgbàlà gbà lọ́dọ̀ ẹnikẹ́ni àfi Jésù Krístì (Ìṣe àwọn Àpọ́stélì 4:12). Àwọn tí wọ́n kọ̀ ọ́, tí wọ́n sì kú ní ipò yẹn yóò kàgbákò wíwà nínú adágún iná, nígbẹ̀yìngbẹ́yìn (Ìwé Ìfihàn 20: 15). Àná ti lọ; òní nìkan ló ń bẹ fún ọ nítorí a kò ṣèlérí ọ̀la fún ẹnikẹ́ni. Ronúpìwàdà àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ ní báyìí, kí o sì gba Jésù Krístì láti rí ìdáríjì gbà, kí o lè jèrè ìyè àìnípẹ̀kun (Jòhánù 3:16). Ọ̀lá lè pẹ́ jù!

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*

*Lúùkù 23:42-43*, tàbí Hédíìsì (ibi ìdálóró, níbi tí àwọn ẹlẹ́ṣẹ̀ ń gbé láti jìyà títí di Ọjọ́ Ìdájọ́, nígbà tí Ọlọ́run yóò sọ wọ́n sínú adágún iná) - *wo Lúùkù 16:23-28*.

Òkú tí ó wà ní Hédíìsì ti ń jẹ oró bayìí. Ó ṣeé ṣe kí ó máa bínú, bí ó ṣe ń rántí àwọn tí wọ́n mọ ohun tí òun ìbá ti ṣe láti má nírìírí oró tí ó pọ̀ tó yìí, ṣùgbọ́n tí wọ́n kùnà láti sọ fún un. Ó sì lè máa kábàámọ̀, bí ó bá jẹ́ pé wọ́n sapá láti kìlọ̀ fún un lọ́pọ̀ ìgbà, ṣùgbọ́n ó yàn láti kọ etí sí ẹ̀bẹ̀ wọn pé kí ó ronúpìwàdà àwọn ẹ̀ṣẹ rẹ̀, kí ó sì jọ̀wọ́ aiyé rẹ̀ fún Krístì. Ó ṣeni láàánú pé kò sí ẹ̀bẹ̀ àti àyè mọ́ láti wá bá Krístì lẹ́yìn tí ènìyàn bá ti kú. Ní ìdàkejì, òkú tí ó wà ní Párádísè ń sinmi ní ibi ìdùnnú ńláǹlà; ibi tí ìtẹ́lọ́rùn wà, tí kò sí ìrora tàbí ìbànújẹ́. Pẹ̀lú ayọ̀ ni ó ń retí èrè tí kò ṣeé díye lé, ní ọjọ́ ìdájọ́.

Ìwọ ńkán? Ṣé o ní ìgbàlà? Ṣé o mọ ohun tí ó ń dúró dè ọ́ nígbà tí o bá kú? Ǹjẹ́ àwọn tí ò ń bá rìn ń bá ọ sọ̀rọ̀ nípa bí ìgbàlà ti ṣe pàtàkì tó? Ǹjẹ́ wọ́n ti sọ fún ọ pé kò sí òtítọ́ nínú ẹ̀kọ́ *'Àtúnwáiyé bíi ẹlòmíràn lẹ́yìn iku'*? Ǹjẹ́ wọ́n ti jẹ́ kí o mọ̀ pé kò sí ẹnìkan tí ó lè ní ìgbàlà nípasẹ̀ iṣẹ́ rere rẹ̀, bíkòṣe Ẹ̀jẹ̀ Jésù Krístì? Krístì ni Ọ̀na kan ṣoṣo sí Ọ̀run. Ó sọ wípé: *"Èmi ni Ọ̀nà, Òtítọ́, àti Ìyè. Kò sí ẹnikẹ́ni tí ó lè wá sọ́dọ̀ Bàbá, bí kò ṣe nípasẹ̀ Mi"* (Jòhánù 14:6). Èyí tó túmọ̀ sí pé, a kò lè rí ìgbàlà gbà lọ́dọ̀ ẹnikẹ́ni àfi Jésù Krístì (Ìṣe àwọn Àpọ́stélì 4:12). Àwọn tí wọ́n kọ̀ ọ́, tí wọ́n sì kú ní ipò yẹn yóò kàgbákò wíwà nínú adágún iná, nígbẹ̀yìngbẹ́yìn (Ìwé Ìfihàn 20: 15). Àná ti lọ; òní nìkan ló ń bẹ fún ọ nítorí a kò ṣèlérí ọ̀la fún ẹnikẹ́ni. Ronúpìwàdà àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ ní báyìí, kí o sì gba Jésù Krístì láti rí ìdáríjì gbà, kí o lè jèrè ìyè àìnípẹ̀kun (Jòhánù 3:16). Ọ̀lá lè pẹ́ jù!

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*